**OWE**

A NJUWỌN ko ṣe wi tejọ ija ilara ko tan boro.

Agbalagbą ti yio tẹ ilẹ tutu yio da omi siwaju. Igba ki i tọ lọ bi orere aiye ki i tọ lọ bi ọpa ibon.

# Irohin Yoruba

No. 760 DECEMBER 30 — JANUARY 5, 1960 Kobo Meji (2D.)

**LAKAYE ỌRỌ**

OJU Oluwa mbẹ lara awọn olododo, eti Rẹ si ṣi si igbe wọn. Oju Oluwa kan si awọn ti nṣe buburu lati ke iranti wọn kuro lori ilẹ. Awọn olododo nke, Oluwa si gbọ, o si yọ wọn jade kuro ninu iṣẹ wọn gbogbo.

# Ẹ KU EWU ỌDUN

## Adura Ọdun Titun

OLỌRUN sọ ninu Ọrọ Mimọ Rẹ pe "Oju mi yio ma a ba nyin lọ. Emi o si fun nyin ni isimi".

Ninu ọdun yi, buburu kan ki yio ṣubu lu wa bẹni arunkarun kan ki yio wọ inu agọ wa.

Yio paṣẹ fun awọn Angẹli Rẹ lati pa wa mọ kuro lọwọ agbako ewu mọto, ewu basikulu, ewu ọkọ-ilẹ, ewu ọkọ-ofurufu, ewu olọṣa, ewu alọnilọwọgba, ewu atẹgun buburu ati ewu ajakalẹarun.

Lọwọ oda ati iyan, ọta ile ati ọta ode, amọniṣeni ati afaimọniṣeni, aṣeni banidaro, afi-oju fẹni ma f'ọkan fẹni, af'ọrọ kẹlẹ baniję lẹhin, alakoba ati aladunrunmọ, alaroka ati agbọyisọyi, lọwọ ogun ati idagiri ati lowo iku ojiji, Oluwa rere gba wa. Aṣẹ.



**OLOYE SAMUEL LADOKE AKINTOLA**
( Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ - Orun )

## Ẹ fi ọpẹ fun Ọlọrun

ENIA iba ma a yin Oluwa nitori ore Rẹ ati nitori iṣẹ iyanu Rẹ lori awa ọmọ enia.

Ẹ fi ọpẹ fun Oluwa nitori O ṣeun ati nitoriti anu Rẹ duro lailai.

Iba ma ṣe pe Oluwa wa fun wa ni, awọn enia buburu iba ti gbe wa ni l'aiye.

Bikoṣepe Oluwa ba ko ile na, awon ti nkọ o nsiṣẹ lasan ni: bikoṣe pe Oluwa ba pa ilu mọ, Oluṣọji lasan.

Gbe Oluwa ga pẹlu mi, ki a si jumọ gbe orukọ Rẹ leke.

Emi ti wa ni ewe, emi si dagba, emi koiti ri i ki i a ko Olododo silẹ tabi ki iru ọmọ rẹ ki o ma a ṣ'agbe onjẹ.

Olododo yio si dabi igi ti a gbin si eti ipa odo, ti nso eso rẹ jade ni akoko rẹ, ati ohunkohun ti o ba nṣe ni yio si ma a ṣe deedee.

Enia iba ma a yin Oluwa nitori ore Rẹ ati nitori iṣẹ iyanu Rẹ si awa omọ enia. Ẹ ma a yin Oluwa ni ojojumọ.

# 1960 CALENDAR 1960

**JANUARY**

| SUN | MON | TUE | WED | THU | FRI | SAT |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | | | | | 1 | 2 |
| 3 | 4 | 5 | 6 | 7 | 8 | 9 |
| 10 | 11 | 12 | 13 | 14 | 15 | 16 |
| 17 | 18 | 19 | 20 | 21 | 22 | 23 |
| 24/31 | 25 | 26 | 27 | 28 | 29 | 30 |

**FEBRUARY**

| SUN | MON | TUE | WED | THU | FRI | SAT |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | 1 | 2 | 3 | 4 | 5 | 6 |
| 7 | 8 | 9 | 10 | 11 | 12 | 13 |
| 14 | 15 | 16 | 17 | 18 | 19 | 20 |
| 21 | 22 | 23 | 24 | 25 | 26 | 27 |
| 28 | 29 | | | | | |

**MARCH**

| SUN | MON | TUE | WED | THU | FRI | SAT |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | | 1 | 2 | 3 | 4 | 5 |
| 6 | 7 | 8 | 9 | 10 | 11 | 12 |
| 13 | 14 | 15 | 16 | 17 | 18 | 19 |
| 20 | 21 | 22 | 23 | 24 | 25 | 26 |
| 27 | 28 | 29 | 30 | 31 | | |

**APRIL**

| SUN | MON | TUE | WED | THU | FRI | SAT |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | | | | | 1 | 2 |
| 3 | 4 | 5 | 6 | 7 | 8 | 9 |
| 10 | 11 | 12 | 13 | 14 | 15 | 16 |
| 17 | 18 | 19 | 20 | 21 | 22 | 23 |
| 24 | 25 | 26 | 27 | 28 | 29 | 30 |

**MAY**

| SUN | MON | TUE | WED | THU | FRI | SAT |
|---|---|---|---|---|---|---|
| 1 | 2 | 3 | 4 | 5 | 6 | 7 |
| 8 | 9 | 10 | 11 | 12 | 13 | 14 |
| 15 | 16 | 17 | 18 | 19 | 20 | 21 |
| 22 | 23 | 24 | 25 | 26 | 27 | 28 |
| 29 | 30 | 31 | | | | |

**JUNE**

| SUN | MON | TUE | WED | THU | FRI | SAT |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | | | 1 | 2 | 3 | 4 |
| 5 | 6 | 7 | 8 | 9 | 10 | 11 |
| 12 | 13 | 14 | 15 | 16 | 17 | 18 |
| 19 | 20 | 21 | 22 | 23 | 24 | 25 |
| 26 | 27 | 28 | 29 | 30 | | |

**JULY**

| SUN | MON | TUE | WED | THU | FRI | SAT |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | | | | | 1 | 2 |
| 3 | 4 | 5 | 6 | 7 | 8 | 9 |
| 10 | 11 | 12 | 13 | 14 | 15 | 16 |
| 17 | 18 | 19 | 20 | 21 | 22 | 23 |
| 24/31 | 25 | 26 | 27 | 28 | 29 | 30 |

**AUGUST**

| SUN | MON | TUE | WED | THU | FRI | SAT |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | 1 | 2 | 3 | 4 | 5 | 6 |
| 7 | 8 | 9 | 10 | 11 | 12 | 13 |
| 14 | 15 | 16 | 17 | 18 | 19 | 20 |
| 21 | 22 | 23 | 24 | 25 | 26 | 27 |
| 28 | 29 | 30 | 31 | | | |

**SEPTEMBER**

| SUN | MON | TUE | WED | THU | FRI | SAT |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | | | | 1 | 2 | 3 |
| 4 | 5 | 6 | 7 | 8 | 9 | 10 |
| 11 | 12 | 13 | 14 | 15 | 16 | 17 |
| 18 | 19 | 20 | 21 | 22 | 23 | 24 |
| 25 | 26 | 27 | 28 | 29 | 30 | |

**OCTOBER**

| SUN | MON | TUE | WED | THU | FRI | SAT |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | | | | | | 1 |
| 2 | 3 | 4 | 5 | 6 | 7 | 8 |
| 9 | 10 | 11 | 12 | 13 | 14 | 15 |
| 16 | 17 | 18 | 19 | 20 | 21 | 22 |
| 23/30 | 24/31 | 25 | 26 | 27 | 28 | 29 |

**NOVEMBER**

| SUN | MON | TUE | WED | THU | FRI | SAT |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | | 1 | 2 | 3 | 4 | 5 |
| 6 | 7 | 8 | 9 | 10 | 11 | 12 |
| 13 | 14 | 15 | 16 | 17 | 18 | 19 |
| 20 | 21 | 22 | 23 | 24 | 25 | 26 |
| 27 | 28 | 29 | 30 | | | |

**DECEMBER**

| SUN | MON | TUE | WED | THU | FRI | SAT |
|---|---|---|---|---|---|---|
| | | | | 1 | 2 | 3 |
| 4 | 5 | 6 | 7 | 8 | 9 | 10 |
| 11 | 12 | 13 | 14 | 15 | 16 | 17 |
| 18 | 19 | 20 | 21 | 22 | 23 | 24 |
| 25 | 26 | 27 | 28 | 29 | 30 | 31 |

# Awọn Onkawe Irohin Yoruba nki nyin ku ewu Ọdun-Titun

NI ibẹrẹ ọdun, o yẹ o si ṣe anfani lati wo ọtun wo osi, ati lati wo ẹhin bojuwo ọdun ti o koja, ki a si bojuwo iwaju fun eyi ti o mbọ. Ti a ba wo ẹhin ao ri awọn aṣeyori wa ati ikuna wa ninu ọdun ti o ti koja; a o si ma a wo iwaju pẹlu ireti ati ohun ti ani lepa, iwọnyi jẹ ohun ti o tọ, ti a si le gbọjẹgẹ fun.

Ṣugbọn, ohun miran ti o tun ṣe pataki ju eyi lọ ti a si ni lati dojukọ ni lati bojuwo ohun ti Ọlọrun ti ṣe fun wa sẹhin, ki a si ran ra wa leti eyiti o tun ṣe loni. Ọlọrun nfi eyi ṣe isura fun


ENI OWO A. S. SOLARIN

* * * *

wa ati ninu iwe Rẹ, o nrọ wa nigbagbogbo lati ṣe eyi pe: "Iwọ nilati ranti ọna ti Oluwa Ọlọrun Rẹ ti mu rin" Deut. viii, 2 Eyi jẹ ofin fun wa, ti a si tẹnumọ ninu Iwe Mimọ eyiti a si ni lati ṣakiyesi dada.

Bi a ba bojuwo ẹhin wo ọdun ti o koja, ao ri apẹrẹ ọwọ Rẹ ninu ohun ti o ti ṣẹlẹ si wa ati awọn iriṣiwa eyiti a nilati dupẹ lọwọ Rẹ fun. Ko dojuti wa ri bi awa tilẹ ti doju ti I....Bi a ti nronu lori awọn nkan wọnyi, a ni lati toro idariji fun awọn ikuna wa. Ki a si tọrọ iranlọwọ Rẹ, pe ki [illegible] le sin In daradara ju t[illegible] atẹhinwa lo.

Ani a ti nbojuwo ẹhin o yẹ ki a gb e ọkan wa lọ si igba ọdun sẹhin, ki a si ran ra wa leti akoko yẹn, eyiti Kristi Olugbala wa di irubọ ẹṣẹ fun wa, ti o ni ẹbi ẹṣẹ wa, ki awa ẹlẹṣẹ le lọ bi alailẹṣẹ lọrun.

Bi a ti nwo iwaju a ko le ri ohun ti o wa niwaju, ṣugbọn a ni ileri ati idaniloju pe o wa larin wa ati pe iranlọwọ Rẹ mbẹ ninu igbesi aiye wa, ati pe idaniloju wa pe ao wa pẹlu Rẹ, ati pe ao ri bi On paapa ti ri. Wo iru anfani nlanla wo ti o si jẹ oto to bayi.

Ki Ọlorun ki o jẹki a le ma a gbe ninu imọlẹ anfani bayi to bẹ ti yio fi jẹ pe ti O ba de, ki a wa ni imura silẹ lati pade Rẹ.

Ẹ ku ọdun, ẹ ku iyedun.

Ẹni-Ọwọ A. S. SOLARIN

* * * *

MO ki ẹnyin ọmọ iya mi l'ọkunrin ati l'birin wipe ,ẹku ewu ọdun ẹku-iyedun aṣeyi-ṣe-amọdun, aṣamọdun ṣemurẹn amin. Ki ẹ mọ daju wipe, ko si ọna kan ti a fi le ri igbala bikoṣe nipasẹ ati Ẹsẹ Jesu Kristi Olugbala, eyi ti o mu wa ri ọdun titun ti a wa yi, ki Oluwa ki o ṣe ọdun yi ni abo fun olukuluku wa ati agba ati ọmọde Amin

Ẹku-ewu-ọdun, ẹ ku iyedun, ki odunni ki o ya abo fun wa, ki Oluwa ki o pẹlu awọn Olotu Iwe Irohin Yoruba ati awọn oṣiṣẹ rẹ ati gbogbo awọn Alakoso Ijọba Naijiria. Ki ọdun 1960 yi jẹ odun Ire-wọlede fun gbogbo wa o. Amin.

Ẹni-Ọwọ Alufa Agba, S. A Ṣọtọmi, Oludasilẹ Ẹgbẹ Kerubu ati Serafu—New Eden Mushin

* * * *

MO ki gbogbo ẹnyin Kristiẹni, Musulumi ati abọrisa pe ẹ ku odun, Oluwa jẹki o ba wa laiye ati la[illegible] Amin.

Nisisiyi ti gbogbo awa ara Naijiria fẹ lati gba Ominira Ijọba Naijiria, ẹ jẹki a w[illegible] ni irẹpọ gidigidi paapa ẹnyin Olori Ẹgbẹ Oṣelu wa. Ẹ jẹki gbogbo wa ṣiṣẹ rere pupọ fun anfani Naijiria, Oluwa yio si ṣe atilẹhin fun wa.

Ẹ jẹki awa obi tubọ ma a


OLOYE T. S. FUJAH

* * *

fun awon ọmọ wa ni ẹkọ dada. Ki Oluwa ran gbogbo ,wa lowọ ati awọn ọmọ wa na pẹlu o. Amin.

Emi ni,
OLOYE T. S. FUJAH
Arẹ Eko.

MO ki gbogbo ẹnyin onkawe "Irohin Yoruba" ati gbogbo ẹnyin araiye ẹ ku ipalẹmọ Odun Nla-ọdun 1960. Oluwa jẹki ẹ se e pẹlu alafia, owo, ọmo ati idunnu, ki Oluwa si jẹki ẹ


OMO-OBA AMINU KOSOKO

ṣe ọpọlọpọ odun miran si i pẹlu idunnu.

Ki Oluwa ran awa obi ọmọ ile-iwe lowọ lati le fun wọn l'ẹkọ ijinlẹ ati lati le jẹki nwon ni iwa rere, ko si anafani kan 'nu iwe inunibini, ilara ati abosi.

Emi ni,
Ọmọ-Ọba Aminu Kosọkọ
Oloye Asajọn Ọlọja Ereko.

* * * *

MO ki gbogbo ẹnyin ọmọ enia laida ẹnikan si, ẹ ku ipalẹmọ ọdun, ki Ọlọrun ki o ṣe e ni abo ọdun fun tọkunrin tobirin wa. Ki Ọlọrun ninu aanu Rẹ tan imọlẹ Rẹ sinu ọkan gbogbo


[illegible] T. DAWODU

Ẹ jẹki a bẹ Ọlọrun gidigidi fun awọn ọmọ wa ki O ṣe won ni ọmọre ki nwọn ma jẹ ọmọ ti yio ma a gbe ita sọko si ile baba wọn. Ẹ jẹki awa na bojuto wọn dada nipa ẹkọ ati iwa wọn, ki a si ma fi owo ile-iwe wọn jafara lati ma a san.

Ki Ọlọrun jẹki a ṣe ọpọ ọdun, ki O si ma a ran w[illegible] lọwọ ki O si da awon ọmọ na si fun wa o.

Emi ni,
I. T. DAWODU
Imam Agba Ahmadiyya
Movement-in-Islam
(Eka Agege).


KO SI ẸNITI O BỌ LỌWỌ

OTUTU IBA










DỌKITA SỌ WIPE




Da OTUTU IBA rẹ duro
Jẹ ki o gbe koro
"ASPRO" mi
ARA RẸ YIO SI TUN YA-GAGA



Oloye Awolọwọ njo pẹlu Iyaafin Rankine aya Gomina Ipinlẹ Iwọ-Orun ni ibi ase apejẹ ti Oloye Awolọwọ pe ni alẹ ọjọ aisun Keresimesi ni ile rẹ ni Oke Ado Ibadan.

## Ọdaran kan ni baba on ni o kọ on ni ole jija

ADO-EKITI.

NI ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kọkadilogun oṣu yi ni Adajọ Kotu Ijọba Ibilẹ (Grade "B" Customary Court) Ado-Ekiti ju ọdaran obirin kan, Ajisafẹ Alari, ẹni ọdun mọkanlelogun si ẹwọn oṣu mẹfa nitori o jẹbi ẹjọ ti awọn ọlọpa fi sun pe o ji agogo-ọwọ obirin kan ti owo rẹ jẹ pọnun mẹta sile mẹta (£3. 3s.) mọ obirin kan ti o njẹ Ajayi lọwọ.

Ọdarn na gba wipe on jẹbi ṣugbọn o bẹbẹ pe ki Adajọ jọwọ ṣe on jẹjẹ, nitoripe, baba on ti o ku ni ọdun 1954 ni o ti fi iṣẹ ole-jija kọ on ni igba aiye rẹ nitoripe ti o ba nlọ si ode ole-jija a ma a mu on dani. Adajọ ko gba ẹbẹ rẹ, o ni ẹṣẹ ti o ṣe ko kan baba rẹ ti o ti ku, ni o ba fi ju u sẹwọn

* *

A fi ifẹ inurere si enia gbogbo ki gbogbo ẹnyin onkawe Irohin Yoruba ẹ ku ọdun, ẹ ku iyedun, aṣeyi ṣ'amọdun o. Amin.

# Aṣeyẹ ọdun Keresimesi



Ọlọla James Robertson Gomina Agba Naijiria njo ijo ajọdun Keresimesi pẹlu Julie Williams ni Island Club l'Eko



Aworan yi ni ti igbati awọn ogunlọgọ ọmọdekunrin a t i ọdọmọdebirin n j o ijo-asiko kan ti nwọn npe ni "BỌN-SUẸ" ni alẹ aisun-ọdun Keresimesi ti o kọja yi ninu ile-ere kan l'Eko.



Ọdọmọdekunrin yi nfi ọti orisirisi gbadun aisun ọdun Keresimesi



O DARA LENU

YIO SI FUN O NI AGBARA





Phosferine Tonic Wine je agbo pataki ti nfun ara ni okun. Mu lojojumo. Yio mu ayo ba o'iwo yio si ri orun sun daradara. Ra igo re kan lowo awon ti nta a *nisisiyi*!

**Akiyesi pataki fun awon aboyun.**

Phosferine Tonic Wine ki panilara. Ko si eran tabi ohun ti a yo kuro ninu eranninure.

# PHOSFERINE TONIC WINE

*agbo ti o gbadun . . .*
*mejetitun nla - yio se o ni ire.*




Aworan oke yi ni ti awọn diẹ ninu ogunlọgọ onilu ti o fi ilu ati orin-kikọ 'da awọn ọlọdun Keresimesi laraya l'Eko ni alẹ aisun-ọdun ti a ṣe koja lọ yi.



IROHIN YORUBA

# IJAMBA PUPỌ ṢẸLE NIUN ỌDÚN KERESIMESI

OPỌLỌPỌ ẹmi ni o ṣofo ninu oniruru ijamba ti o ṣẹlẹ ninu ajọyọ ajọdun Keresimesi ti a ṣe kọja yi kakiri gbogbo agbaiye.

NI APAPỌ ILU AMẸRIKA, enia mọkan le nirinwo (401) ni o ku iku jamba nibẹ, iṣẹju mẹjọ-mẹjọ sirawọn ni ijamba fi npa enia kọọkan. Ninu awọn ti o ku wọnyi, ọgbọn o le ni ọọdun (330) enia ni o ku iku ijamba mọto loju ọna. Ni ilu Wisconsin, Baba Arewe-yọ odun Keresimesi (Santa Claus) kan ni ẹniti o kọkọ ku ninu ijamba mọto nigbati mọto rẹ takiti doju-delẹ.

NI SOUTH AFRICA (Iha Gusu Ilẹ Enia-dudu)—enia mejileladọrin (92) ni o ku, gbogbo wọn si jẹ kiki enia-dudu t'nwọn ba ara wọn ja ajaku, enia mẹrindinlogun pere ni o ku iku ijamba mọto ninu wọn,ẹgbẹta (600) enia ni Ile-iwosan Johannesburg ṣe itọju ọgbẹ fun.

NI ILU SARO (Freetown), enia mẹtala (13) ni o ku iku ijamba, ogun (20) enia ni o si farapa ni alẹ aisun Ọdun Keresimesi nigbati ọkọ Reluwe kan ti ero kun inu rẹ dada fo kuro loju ọna-irin rẹ ti o si takiti doju delẹ ni iṣẹkọrọ ọna Bauya, ti o jinna ni buṣọ mejidi-logọta si Ilu Saro.

NI ILU BENEVENTO SICILY—ọkunrin agbẹ kan ti orukọ rẹ njẹ Armando ba Bagnara, ẹni ọdun mẹrin-diladọta, ati ọmọ rẹ ọkunrin pẹlu ọmọ rẹ obirin, ku iku ijamba majele nigbati nwọn jijọ jẹ onjẹ ajọyọ Ọdun Keresimesi tan. Iyawo rẹ ati awọn ọmọ rẹ keekeeke mẹta miran si tun npọka iku.

NI ILU NAIROBI NI ILẸ KẸNYA, ọkunrin oluṣọ odo omi-tutu kan ti o njẹ Lewis John Summerskill, ẹni ogun ọdun ku iku ijamba mọto, ati ẹnikeji rẹ kan Elmer James Fry, ti iṣe oluṣọ bakanna si farapa lọpọlọpọ nigbati enia-dudu kan gun mọto-alupupu kọlu won ni opopo ọna Nakuru ni Kenya nigbati awọn me-jeji jijọ nrin lọ ni alẹ aisun Ọdun Keresimesi •

LỌNDỌN.—Ọpọlọpọ enia ni o ku iku ijamba mọto ni ilu Lọndọnu ni alẹ aisun Ọdun Keresimesi. Ni ọjọ keji ti iṣe ọjọ Abamẹta, oji nla kan yipo gbogbo Ilẹ Gẹẹsi lerin ti aara pẹlu oji ti o ja kọja ni alẹ aisun Keresi-mesi kakiri Iha Gusu ati Iwọ-Orun Englandi, o ba ọpọlọpọ nkan jẹ, o si pa ọpọlọpọ ẹmi run. Lori gbogbo rẹ, enia mẹtadilọ-gbọn ni nwọn ṣe irohin pe o ṣofo ẹmi won ninu ijamba ti o ṣẹlẹ nibẹ na.

NI ILU NICOSIA, ẹniti o ngbẹnuṣe fun Ẹgbẹ Ogun Gẹẹsi sọ wipe, Ijọba yio ṣe iwadi nipa iku Kọburu kan ti o njẹ Phillip J. Todd, ẹni ọdun mẹrindilọgbọn ti o jona ku sinu ibudo rẹ ti o jona ni aro ọjọ Ọdun Keresimesi.

NI ILU INNSBRUCK ni ilẹ Australia, oji nla kan gbe ọkunrin arinrin-ajo ara Jamaani kan, ẹni ọgọta ọdun lọ soke firofiro ga to ẹẹdẹgbẹta o din mẹwa ẹsẹ bata (490 feet) o si ku ni-gbati o balẹ, eyi ni o ṣẹlẹ si ọkunrin arinrin-ajo na ni-gbati o gun ori oke kan, Gruebel Spitzẹ lọ, eyi ti o ga ni ẹgbaarin din okoole-rugba ẹsẹ bata (7,780 feet) soke lẹba ilu kan ti o njẹ Lennarsbach ni ile Austra-lia Tyrol ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kẹtadilọgbọn oṣu yi.

NI ILU EKO, Ọga Iṣẹ kan, Ọgbẹni Peters, ti iṣe Ala-mojuto Iṣẹ ninu Ile-iṣẹ Apapọ Ijọba Naijiria ku lẹsẹkẹsẹ nigbati ijamba ṣẹlẹ si mọto-ayọkẹlẹ rẹ l'Ebute-Mẹtta larin igbati nwọn nṣe "faaji" ajọdun Ọdun Keresimesi l'Eko, ọkunrin kan si tun ku sinu ijamba mọto nigbati ẹnikan fi mọto-alupupu gbe e ṣanlẹ ni iṣẹkọrọ ọna Denton si Ebute-Mẹtta.

Larin gbogbo ijamba mọto mẹtalelogun ti o ṣẹlẹ ni Eko ati ni Oke-odo Eko larin igba ajọdun Ọdun Keresimesi yi, meji pere ti a daruko kẹhin yi ni enia ku sinu rẹ. Ina kan si tun ṣẹlẹ ni Ebute-Mẹtta, ile mẹfa ti o fẹgbẹ kan ara wọn ni o jona nibi.

# Mo kin Akibu Alarape lẹhin

Late oju ewe Ikerinla

aitete rọmọbi na lelori, nwọn a ti gbagbe pe lati kekere ni awọn ti fi iwa agbere bi olu-ọmọ wọn da sita fun ẹni-ẹleni, nwọn a ti gbagbe igbati nwọn ṣe agbere, ti nwọn kilọ fun wọn, ti nwọn ko fẹ.

Awọn agbalagba npowe kan bayi wipe "Ikun njọ-gẹdẹ ikun nrẹdi, ikun ko n[illegible] pe ohun ti o dun ni i pani". Nipa ti awọn Woli Eke, ti nwọn npuro pe ti Oluwa ni awọn nṣe, ṣugbọn ti nwọn nfi ojojumọ-aiye ṣe ifẹ-inu ara tiwọn nipa iwa agbere, bi awọn miran ba ngbadura fun obirin nitori ki o le ri ọmọ bi, nṣe ni nwọn npadida sọ obirin na di tiwọn, "Potogi ko jẹki a da Oyimbo mọ sọtọ" awọn Woli-Eke ti ba awọn Woli Ojiṣẹ Ọlọrun jẹ. Mo dupẹ lọwọ Olotu pupọ fun aye t[illegible] o gba mi, iṣẹ rẹ ko ni dibajẹ o.

O digba.




Printed and published by the Amalgamated Press (of Nigeria) Ltd., 5/7, Apongbọn Street, Lagos (Editorial) and Advertisement Office) Telphone 23675, 23676. Fun owo "Irohin Yoru-ba" ọdun kan, Eko sile mẹjọ ati kobo mẹjọ (8/8d.). Ilu miran ni Naijiria ati Oke-Okun sile metala (13s.) Olotu S. M. Ademuyiwa, 9, Chapel Street, Lagos.